# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,698 TUESDAY FEBRUARY 15, 1966 (2D

## Enia Marundinladoje Tun Ti Pada Si Iwo Orun

IBADAN:- Ninu irohin to tun de ọwọ wa lati ọwọ oniwe irohin wa ni ilu Ibadan ni o ti ṣe alaye pe enia marundinladoje ninu awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti o lọ ṣe atipo sibi kan lati ọdun to kọja lori rogbodiyan to bẹ silẹ ni Ipinlẹ na eyiti o mu ọpọlọpọ awọn enia Ipinlẹ na lo sa asala fun ẹmi wọn.

Ni ọsẹ to kọja lọ yi ni irohin kan de ile iṣe wa eyiti irinwo (400) enia padabọ si Ipinlẹ Iwọ Orun lati ilẹ Dahomey lẹhinti awọn enia na ri pe awọn ọmọ ogun ilẹ Naijiria ti gba eto akoso Ijọba lọwọ awọn ẹgbẹ oṣelu to nṣe tẹle.

Ninu awọn enia marundinladoje (125) ti nwọn ti padabọ si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ibiti nwọn lọ ṣe atipo si ni awọn enia lati ẹkun Ondo.

Awọn enia na to ṣẹṣẹ pada si Ilu na eyiti o jẹ pe gbogbo awọn enia marundinladoje si jẹ lati ẹkun Ondo eyiti o jẹ pe pelu Ọlọpa lo si bẹrẹ si ni ṣo awọn enia na titi nwọn yio fi mu wọn de ile wọn.

WO OJU EWE KEFA

# IJỌBA OLOGUN SAN'WO OṢU FUN AWỌN ỌBA TI DẸMỌ DA DURO !

IKẸNNẸ:- Gbẹgede gbina ninu gbọngan nla ilu Ikẹnnẹ nigbati ọgbẹni Adebayọ Ogunsanya sọ fun Ogunlọgọ ọkẹalmoye awọn Ọba, Ijoye, Dọkita, Loya, akọwe ibi Iṣẹ - Ijọba ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi wipe, Ijọba Ologun orilẹ ede Naijiria ti san owo-oṣu fun gbogbo awọn Ọba ati Ijoye ti Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ da owo oṣu wọn duro ninu ọdun to kọja lọ yi.

Ọgbẹni Ogunsanya fẹrẹ ma ti sọ ọrọ yi tan, ti gbogbo awọn enia ti nwọn wa ni ibẹ ni ọjọ na fi ho ge e, ti gbogbo wọn nrẹrin idunnu ti nwọn si tun pa atẹwọ ti nwọn tun nfo soke.

Irohin fi ye wa wipe fun nkan bi iṣẹju mẹdogun ni awọn enia na fi ho ge e, ti Ọgbẹni Ogunsanya si da ọrọ rẹ duro na nitori ariwo.

Ọgbẹni Ogunsanya tun sọ fun awọn enia na wipe, Ọlọla Adekunle Fajuyi lo paṣẹ wipe, ki Ijọba Ibilẹ Rẹmọ yara tete san owo oṣu fun awọn Ọba na kiakia.

Onirohin wa kan ran wa leti pe, ni ibẹrẹ ọdun ti o kọja yi ni Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ da owo oṣu awọn Ọba na duro, ti nwọn si sọ owo oṣu wọn di kọbọ kan (1d) lọ'dun.



ỌBA AKINSANYA
Ọdẹmọ ti Ishara

Oruko awọn Ọba na ni wọnyi: Alaiyeluwa Moses Awolesi, Akarigbo Ọba Ijẹbu Rẹmọ Ọba Samuel Akinsanya, Ọdẹmọ ti Ilu Iṣara, Akindoyin Awomuti, Ọba Ikẹnnẹ Ganiyu Atobi, Ẹlẹpẹ ọba Ẹpẹ, Ajalọrun Awero, Ọba Ije u Ife, Olowu Ọba Owu, ati Ladepo Bile Odọladalepo.

Nigbati Ọdun pari, kọbọ kan ni Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ sọ pe ki nwọn fun awọn Ọba wọnyi. Fun nkan bi oṣu mẹsan ni Ijọba ko ti san Owo-Oṣu fun awọn Ọba na, Ṣugbọn ninu Ọsẹ ti o kọja lọ yi ni Ọgagun Fajuyi, Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun paṣẹ wipe ki nwọn tete san owo oṣu fun gbogbo awọn Ọba na, Ijọba si ti san gbogbo awon owo ti Ijọba ko san fun won lati ẹhin wa.



**Ọlọla Adekunle Fajuyi**
Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun

Awon Ọba na ti gba owo won lati igba ti Ijoba ẹgbẹ Dẹmo ti da duro.

Ni ipari ọgbẹni Ogunsanya tun sọ pe gbogbo awon oṣiṣẹ iṣẹ Ijoba ti ẹgbẹ Dẹmo ti daduro ni Ijoba Ologun yio gba si iṣẹ pada nigbati nwon ba ṣe iwadi won tan.

Irohin fi ye wa wipe nitoripe awon Ọba na ko lati ṣe ẹgbe Demonu ni Ijoba ẹgbe Demo ba fi da owo oṣu won duro ṣugbon ọlọla Adekunle Fajuyi ti paṣẹ, nwon si ti san owo na fun won yoto mi ni gbogbo awon Ọba na wa nisisiyi.



ỌBA AWOLESI
Akarigbo Ijebu Remo

Awọn miran ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti'e ti tun da awọn Ọba na laamu ti nwon si nsọ wipe awon yio yọ Ọba na kuro ni ori Oye bi nwọn ko ba ṣe ti awọn.

Ṣugbọn nisisiyi, ko si eniti o gburo awọn enia na mọ, gbogbo wọn wọle bamubamu.

Awon miran nfi esun eke sun awon Ọba nigbana wipe, awọn yio yọ wọn kuro lori oye nitoripe, nwon ko ṣe ohun ti o tọ si ara ilu fun awọn.

Gbogbo rogbodiyan ti o ti wa ni adugbo na ni enikan ko tun gburo wọn mọ nigbati Mejọ gẹnara yi.

# ỌRỌ ỌLỌRUN KO MU IJA LỌWỌ, ALAYE NI

Eleyi jẹ ohunti o ya mi lẹnu nigbati mo ri ninu Iwe Iroh'n Imolẹ ti ojo kewa oṣu yi e iti aw'n ẹlẹsin Ọlọrun meji kan npe ara won ni Aṣiwere, Ọlọrun Ẹlẹda wa Ọlọrun owu ni ki a maṣe titori rẹ pe ara wọ ni were, Ọlọrun lo gbọn'

**Lati Owo**



Alufa M. A. Abinusawa

Gẹgẹbi a ti mọ pe otito ei la ni Jesu kirist ti a bi ninu obinrin ki o le gba gbogbo araiyẹ la Galatia 4:4 Ọlọrun ran ọmọ rẹ jade wa eniti a bi ninu obinrin ti a bi labẹ ofin siwaju si (I kon lnti 2: 5) Nitori Ọlọrun kan nbẹ on ni nibẹ onilaja kan pẹlu larin Ọlọrun ati enia on paapa enia, a ni krist Jesu

Eleyi fi han wa pe Ọlọrun ni Jesu Iṣe bi a tiẹ bi ninu obinrin bẹẹni a rin ka ninu kuraani pe Ọlọrun sọ pe ẹmi yio yan ọmọ kan fun ara mi mimọ ni ọmọ na yio jẹ ohun gbogbo ti nbẹ laiye ati ni orun ni yio jẹ tirẹ nitori on ni ipilẹṣẹ owo Ọlọrun ti orun(Suratu 2 aya 116 187 Bakara.

**JESU ỌMỌ ỌLỌRUN NI**

Eleyi fi han wa pe Jesu tiwa ni orun Ṣ ju aiye gbogbo a ko si sọ ira ọrọ yi fun awọn Woli Ọlọrun miran ohun pataki ti mo fẹ sọrọ le lori ni pe awọn Elesin Igbagbo pe Jesu krist ọmọ Ọlọrun ni

Jesu ni yio si ma ṣe idalẹ aiye ni ojọ igbende ti a pe ni ajinde Ninu mathew 3; 17 ari ka wipe nigbati Jesu ti ọwọ Johannu ṣe itibọmi (Baplism) orun si ṣilẹ gbogbo awọn ti o wa nibẹ ni ojọ na si gbọ ohun to fọ lati orun wa wi "Eyiyi ni ayanfẹ ọmọ mi eniti inu mi si dun gidigidi (mark 1; 11) tun jẹri si eyi bakanna ni (Luku 1: 31-32) Maria yio loyun yio si bimọ Ọkunrin kan ao ma pe oruko rẹ ni 'Jesu on yio sọ ọmọ Ọga-Ogo ni ao si ma pee.

Eleyi si jade lati ẹnu Angel Gabriel (Jubril). Bi awa Elẹsin Kristi na ka eleyi ninu Bibeli mimọ ti awa tẹle, o yẹ ki a gbagbọ pe Jesu ọmọ Ọlọrun ni ati Olugbala gbogbo araiye si ni pẹlu.

Ni ọna keji ti a ba tọ ọna ti Jesu Kristi ti gba wa si aiye lati iran baba nla wa Abraham (Anabi Braimọ) ao ri pe ko yẹ ki awọn ti o jẹ Onigbagbọ pe ara wọn ni ẹru Ọlọrun nitori lati ọdọ Abraham (Anabi Braimọ) ni igbagọọ ti bẹrẹ Abraham Anabi Braim) lo bi Isaki on na lo si bi Ismaeli Iya Isaki Sara i a Ismael Hagari, ṣugbọn ẹru ni Hagari Iyawo Abraham ni Sara. ti a ba sọrọ rẹ Obinrin ọkọ kanna ni awọn mejeji awọn mejeji lo si bimọ fun ọkọ wọn otitọ ni igbesi aiye awọn ọmọ na, otitọ ni ṣugbọn Iwe mimọ ko sọ fun wa pe baba Ismael sọ orukọ rẹ ni "ẸRU"

Bi ọ tilẹ jẹ pe Ẹru lo bi ọmọ na Ẹmi ro ninu ara mi pe bi a ṣe bi Ẹru tabi Ẹni-binrin ṣe mọ ni iyawo na ṣe bimo ọkan ko yatọ igbe si aiye wọn le yatọ gẹgẹbi mo ṣe sọ bẹ na lo ṣe wa loue oni pẹlu ọmọ Alarede tabi oniyigi pẹlu ẹniti a fẹ lasan Iaisi yigi lori rẹ tabi ẹmọ ti a bi si ita ti iya re ko ba ọkọ re gbe inu ile.

O si ye ki eleyi ye wa ju bi ti ṣe sọ lọ, ṣugbọn baba kọna ni

**BABA KAN KO JẸ PE ỌMỌ RẸ L'ẸRU**

Ko si baba kan ni aiye y to jẹ pe ọmo re ni omo ale tabi omo eru omo ni omo njo Ọlorun lo mo Isu ti yio kehin ogba opolopo o ti nwon npe ni omo ale lo nlt ri ju omo oniyigi lo t bi omo Alarede ti oko fi ey. ti be nibe mo fe ki a ka itan Abrham titi de itan se Jesu krist ki e si fayo fun mi tabi so fun mi ibiti omo Ẹru ti here

**ẸBẸ**

Mo be enyin onkawe yi lati toka si fun mi biya ni nu karun ti a ti eniken ni

WO OJU EWE KẸRIN

# KERE O! KERE O!!

## Awọn Tani Wọnyi ?



LATI ỌWỌ OSI:- ỌNI ADELẸKAN (Olubuṣe) ENIKEJI:- ỌNI ADEMILUYI (Ajagun) ẸNIKẸTA: ỌNI ADERẸMI (Atobatele)

**AWON ỌMỌ ODUDUWA META TO JOYE 'ỌNI,' TI LE ARA WỌN**

**ITAN WỌN DUN KA**

Njẹ o ti ka ninu itan Igbesi aiye Oduduwa ati ti awọn ọmọ rẹ" to ṣẹṣẹ jade?

Bi o ko ba ti ra a, maṣe jafara, ni ẹrọpe, bi awọn awon "ỌNI" mẹta yi ti ṣe itan iyanu ia ti le ra won papọ, tẹni itan wọn wa ninu Iwe na.

Maṣe ki nwọn ro hin re fun o, Iete lo ra tire loto tan, 3/- pere ni, Postage 9d

F'owo tirẹ ranṣẹ si:—

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria.
(Leti ọja Jankara)

OLOTU

# Iwe si Olotu Irohin Imole

## Mo kan saara si Ogagun Ironsi

Olotu:- Jowo gba mi ni aye rampe ninu iwe nyin to nta bi akara gbigbona lati kan saara si Gomina Ologun fun apapo Ijoba ile Naijiria Ogagun Johnson Aguiyi Ironsi fun ipo ti o gbe orile ede Naijiria lojo oni ati ise nla ti o se lati le da awa omo ile Naijiria si titi di ojo oni ti o si tun gba wa sile iowo awon Ijoba egbe oselu to fe so ile Naijiria di ile yepere ni orilede Afrika,



Oga'gun Aguiyi Ironsi

Adura mi si Ogagun Ironsi ati awon yoku re ni pe ki Oluwa je ki nwon se ise won ni a se yori eyiti nwon yio fi gbe ogo ile Naijiria yo ju bi o tise wa bayi.

Ninu ise nla ti a nfe ki Ogagun Ironsi ati awon omo lehin re se ni pe ki nwon ba wa mu oju to awon olopa orile ede yi nipa iwa ti awon olopa na ti hu sehin ati awon oloja ti awon olopa na ko fi lokan bale eyiti awon oloja ko ni anfani lati ta oja won mo.

Ninu iwa awon olopa to ma mu awon to nta oja na ni pe ti nwon ba ti mu awon oloja ti nwon gbe oja won de Tesan won nwon yio mu eyiti o wu won ninu awon oja na ati pe eleyi ko si ba oju mu inu wa yio dun bi Ogagun Aguiyi Ironsi ba ti ba wa mu oju to eyi ni kiakia.

Emi ni
Okiki Ega

EKO

## Ilu Omupo Dupe Lowo Ijoba Ologun

Olotu, Inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye die ninu iwe yin to kun fun ogoyn ati oye ti o si tun nta bi akara gbigbona lati du pe pupo lowo Ijoba Ologun ile Naijiria ati paapa julo Gomina Ologun fun akitiyan re lati le mu alafia wo orile ede ile Naijiria fun omode ati agba.

Beeni a tun dupe pupo lowo awon enia jankanjankan ti nwon tun sowopo pelu Ijoba Ologun ile Naijiria. Bakanna ni awo omo egbe Alenil, re ilu Omupo tun dupe lowo Ijoba Ologun ile Naijiria nipa eto alafia ati ifokanbale to tun pada bo sile Naijiria.

Mo tun fi oro mi yi kowo lati kesi awon omo ile Igbomina lati ni isowopo pelu Ijoba Ologun na lati le mu alafia wo ile wa paapa fun Ogoyan wa J. K. Balogun ti ise Alaga egbe odo Afenifere ti ile Igbomina lori akitiyan re Olorun ko ni jeki o re o awa omo ilu Omudo l'omode l'agba ti duro sinsin lati le ran o lowo nida eto ti o nse lori eto ile Igbomina.

Olotu mo dupe pupo oko oba ko ni ba oyin ise o.

Emi ni
L. A. Asande Ogun
Omupo-Igbomina.

AT LAST THE WATCH WITH A PERSONAL TOUCH
WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

Réf. N° 55. PHOTO



A Wonderful 15 Jewel lever shock protected movement, non magnetic, unbreakable mainspring ROLLED GOLD water-proof case and stainless steel back with your name engraved.

and YOUR PHOTO reproduced IN COLOR on metal dial

PRICE £ 5.

HURRY SEND YOUR PHOTO (any size) with cash or cheque

WINDSOR
19, Avenue de Lérins – Cannes, France

GBOGBO ARA ILU NKO ORIN IYIN ATI OGO NIPA DYNAMIREY TONIKI

ALE-IBI-ALE Egbogi To ki amonu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mo daju fun Agbara ati Ajebidan se lira agbalagba Okunrin ati Obinrin gbogbo



Bi are ara ba nmu o, ni gbakugba fun wahala tabi ise sise ti o ko le jeun dara dara, tabi ki o male sun da da de okan losan tabi awon san ara re gbogbo ki se fun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunle daradara won ise tabi wahala sise tabi inu awon ailera gbogbo nyin ti ojo ori (age) ba ti koja ogbon odun si adorin tabi jube lo mo daju pe DYNA MIREN ni egbogi ti o nfe lati so ara re di otun pata oju re yio si wale te kete alafia ati Igbadun de Bere Dynamiren yi ni Sobu awon i-

Waterloo Medecine Stores
8. Palm Church Street P. O Box 333 Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.
ADEDUN CHEMIT
14, Wakeman Street
ATI NI SOBU
SB OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA IBADAN

a successful future means planning *Now!*

Have you planned for the security of your family's future? Start a programme of Life Insurance NOW.

*with*

**GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,**
(INCORPORATED IN NIGERIA)

Enquire now for full details of our low cost endowment policy.

HEAD OFFICE:

39/41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2314, LAGOS
TELEPHONE 25251.

BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA.

# Oro Olorun Ko Mu Ija Lowo

## Lati Oju Ewe Keji

Ẹru Ọlọrun? Kini o fa ti a fi pe ni Ẹru Ọlọrun. Nibi ni ẹnyin ti ri ninu kurani pe Muhammed Ẹru Ọlọrun ni oruko rẹ Inu mi yio dun tẹ ẹ ba le tọka rẹ ninu Sararu gbogbo Modupẹ.

## Ija Ko To Rara

Bi a ba ronu ko tọ ki awa ẹlẹsin ma ba ara wa ja rara wakati marun na ni ojojọ nlọ fun adura ati adura pataki ni oru, ọmọ baba kanna ni gbogbo wa işe Iya wa ni ọtọrọ bi a ba siro rọ ni ọna ti iran.

Ẹnyin ngbawẹ awa na si ngba awẹ ati pẹlu ẹnyin nyan Saka wa na nda idamẹta aşẹ Ọlọrun si ni. A nşe itọrẹ anu ẹnyin nşe saara ati bẹbẹ lọ.

## Işẹ Iyanu Jesu

Jesu şe işẹ Iyanu ti a ri ka ninu Bibeli wa Jesu la oju Afọju o ji Oku dide owo Adẹtẹ san ati bẹbẹ. Bi Anabi Muhammed ba şe eyi awa ko mọ boya awọn to ka kurani jinlẹ le sọ.

Şugbọn ohunti a mọ nipa rẹ ni pe laisi egan Woli Ọlọrun ni mo bẹ Ọgbẹni R. A. Dunmoye ati awọn ẹgbẹ Ẹlẹşin lati mu suuru pupọ nitoripe Kogberegbe pẹ awọn ti ko gba Jesu bi ọmọ Ọlọrun ni Aşiwere. Emi da ẹjọ na şugbọn mo le sọ pe Kogberegbe ko ti şọ gbe ọrọ na kalẹ ni o fi fe gba edealyede. Lakotan ọrọ mi ẹniti o je Aşiwere ni ẹniti o sọ pe Ọlọrun ko si Psalm 53 ese 1, O digba die.

## YE IRAWO RE WO

AQARIUS (Jan 22 Feb 20) Iwọ yio gbọ irohin owo yebiye kan loni fi ọkan si ki o si gba a gọọ ki o ma ba padanu.

PISCES (Feb 21 May 20) Ohun kan ti iwọ şe laipe yi; iwọ yio ri anfani lọpọlọpọ.

ARIUS (May 21 April 20) Lo ọgbọn ati laakaye rẹ die nipa oro ara rẹ ki o ma ba fi ara rẹ wu ewu.

TAURUS (April 21 May 20) Nipa ọgbọn asa rẹ ni iwọ yio ri yege ninu ohun kan ti ongbero lati şe ni ọjọrọ

GEMINI (May 21 June 21) Iwọ ailero ninu tinhu ni yio ko o si voyọ loni şọra rẹ gidigidi ki işe ma ba bo nwọn rẹ ni owuro yi.

CANCER (June 22 July 22) Gbogbo awọn ohunti o ba da owo le loni ni yio yọri si rere, şugbọn şọra pẹlu oro ti yio maa jade lẹnu rẹ loni, nitori awọn abinu ẹni

LEO (July 23 Aug 23) Ọgbọn inu rẹ ni ki o maa lo loni ma si se ba enia kan ko ẹgbẹ papọ ki nwọn ma pa se ye imoran rẹ yatọ si ohunti o fẹ se

VIRGO (Aug 24 Sept 23) Awọn enia nla kan yio şe iranlowọ fun ọ loni ti yo ri fi ọkan rẹ balẹ ninu gbogbo ohunti o ba nse, nitorina, maa yaju si ẹnikẹni

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Inu rere rẹ yio gbe o ko olorireken loni ti yio mọ iyi işẹ ti o nşe ni ọna ti yio fi yin o ni ọna ti yio mu iwuri wa fun ọ

SCORPIO Oct 24 Nov 22) Iwọ yio ri ẹbun nla kan gba lọwọ ẹnikan ti o mọ iyi ati imore ise rẹ loni Gbo gbo enia lo ngbadun işe owo rẹ, maşe yi iwa rẹ pada,

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Iwọ yio ri irohin ayọ kan gba loni ti yio mu inu rẹ dun, bẹẹni gbogbo nkan ni yio si dara fun ọ ni alẹ loni

CAPRICORN Dec 22 Jan 21) Ọgbọn inu rẹ ati iwa pẹle yio jẹki o se oriire loni ninu ohun kohun ti o ba da wole lati şe


# KERE O

Nje o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA toşe şẹjade ?

Ha ! Kosemani ni iwe na jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan Işẹdalẹ Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Maşe jẹki nwọn rohin itan ilu rẹ fun ọ

3/- pere ni. Postage 9d

Tete fowo tirẹ ranşe si:-

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE

8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria



## IWE KOŞEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da şe AYẸWO fun ara rẹ

KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta:- Postage 9d

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE

8, Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria (Leti Ọja Jankara)



The NEW HOOVER
Washing Machine
Makes Clothes
Whiter and Brighter
It's easier the ...
HOOVER way

The NEW HOOVERMATIC washes ... rinses spins dry 6lbs. of clothes in 8 minutes all in one continuous operation. That's the amazing performance of the new Hoovermatic a combined Washing Machine and Spin Dryer.



AVAILABLE AT
LEVENTIS TECHNICAL
MARINA — IDDO — IBADAN —
KADUNA — JOS — KANO —
P. HARCOURT — ABA
and Kingsway Stores.

# Ọkunrin Alaini Iṣẹ Kan Wẹ'wọn Ọdun Mẹrin

YABA. Ni ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni Adajọ Kotu kekere ti Yaba paṣẹ pe ki ọkunrin kan ti ko ni iṣẹ lọwọ Abubakar Makurdi yara lọ fi ẹwọn odun mẹrin peiu iṣe alaṣe kara jura lori pe ọdaran ọkunrin na ji pọnun marun (£5) gbe

Ninu ọrọ ọlọpa to ba ọdaran na ṣe ẹjọ ni o ti ṣe alaye fun kotu pe ni ọjọ kọkandinlogun oṣu kẹfa ọdun to kọja lọ yi ni Abubakar Markurdi lọ ji pọnun marun (£5) eyiti iṣe ti ọgbeni Ilu Kano ti o ngbe 40, McCullum Street Ebute-Metta.

Ọlọpa to ba ọdaran ṣe ẹjọ tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ fun ile ẹjọ na pe ọdaran na fun Ilu Kano pọnun eyiti iṣe aiyederu kọrẹnsi ti ọdaran na si gba pọnun marun miran lati fi parọ pọnun marun ti iṣe kọrẹnsi eyiti ko dara.

Ninu ọrọ ẹdaran na lati fi gba ara rẹ siiẹ ninu ile ẹjọ na ni o ti se alaye pe on ko fun ogbẹni Ilu Kano ni owo kankan tabi pe ki on fun ni owo lati parọ rẹ fun on. O ni on ko fun Ilu ni owo kankan.

Adajọ ile ẹjọ na kuna lati gba ọrọ ọdaran na o si ni ki o yara lọ fi ẹwọn ọdun mẹrin jura.

# Ẹni-Oyinbo



Aworan Oke ti ẹ nwo yi ti eni Oyinbo alarabara (Carpet) ti nwọn ṣẹṣẹ nṣe ninu Ile iṣẹ kan ni Orilẹ ede Rọṣia.
Ẹni na dara pupọ, o si ni alogbo fun ọjọ pipẹ.


BERE FUN OJULOWO EGBOGI –

## "Congreve's Iodo Form—Oinment



Atamataṣe ni egbogi" ADIELEGBO" yi je fun itọju gbo bo oriṣiriṣi "EGBO—ẸSẸ" ni kiakia bi o ti wu ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ni bi ẹri gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo yi o ba jin sinu yio jeti oju re hu wa soke, yio si pọn daradara tun bakanna ko si mo werewere ni yio si san patapata Alafia de si ọ nlyen ! –

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won abssale iwe yi ni ogbe ranṣe lọ ra. Bibeko awon Elerẹ ihii on ijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba rarao

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Oja Faji)
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos

## Ha Kini Eleyi




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara jui gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ti idu ,

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si danwo; iwọ yio ri bi o tiṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti Iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu orl erin mẹta ni nwọn mu fun ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ti itaja kakiri Orilẹ ede yi

Distributor

AMOS GBENLE & BROTHERS
34: Docemọ Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,698 TUESDAY, FEBRUARY 15 1966 (2D)


## Enia Mẹwa W'ẹwọn Ọgọfa Odun

GHANA:– Ni ọjọ eti ti ise ọjọ kọkanla oṣu yi ni irohin de ile iṣẹ wa lati owọ oniwe irohin wa ni ile Ghana pe adajọ ile ejọ giga ti ilẹ Ghana ti paṣẹ pe ki awọn enia mẹwa kan ti nwọn jẹ ọmọ ile Ivory Coast yara lọ fi ẹwọn ọgọfa ọdun jura lori pe awọn enia na lodi si ofin Ijọba Ilẹ Ghana eyiti awọn enia na si wọ ilu Ghana laini iwe aṣẹ lọwọ

Ninu ọrọ ọlọpa to ba awọn ọdaran mẹwa na ṣe ejọ ni o ti ṣe alaye fun ile ẹjọ pe ni oṣu to kọja ni awọn alakoso eto ibode ri awọn enia na mu nigbati nwọn fẹ bọ si ẹnu aala ile Ghana ati Ivory Coast laigba iwe aṣẹ ti nwọn yio fi lọ si ilẹ Ghana

Ọlọpa to ba awọn ọdaran mẹwa na ṣe ẹjọ tun ṣe alaye pe nigbati awọn ọdaran mẹwa na ngbero lati salọ ni ẹnu aala ilẹ Ghana lati ilẹ Ivo y Coast ni awọn alakoso oju ibode ilẹ Ghana ba ragabu awọn enia mẹwa na, adajọ kotu na si paṣẹ pe ki awọn enia mẹwa na lọ fi ẹwọn ọgọfa ọdun jura.

# BALOGUN TUN DI ALAGA ẸGBẸ AFẸNIFẸRE IGBOMINA

ẸKO:— Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gbero fun ogunlọgọ ọkẹaimoye awọn ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ti ilẹ Igbomina ẹka Eko ti pesẹ sibi ayẹyẹ Ipade ti awọn ẹgbẹ ọdọ na ṣe lati yan Oloye titun fun ọdun 1966 si ọdun 1967 eyiti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ilẹ Igbomina ẹka Eko se ni ọjọ Abamẹta ti Iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni Ijaiye Street, Eko.

Nigbati o di deede agogo mẹta ọsan ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn jẹ enia jankanjankan awọn onisọwọ ati awọn Agbẹjoro ti nwọn jẹ ọmọ Ilẹ igbomina ti nde sibi ipade ti nwọn yio ti yan awọn Oloye titun na:

Nigbati o di deede agogo marun Irọlẹ ọjọ na ni gbogbo ile ti kun ti ọkẹaimoye enia ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na ko ri aye joko ninu ile mọ

Ki eto yiyan awọn Oloye titun na to bẹrẹ ni awọn ọmọ ẹgbẹ na yan Ọgbẹni Joseph Abegunde gẹgẹbi Alaga eto ipade lati yan awọn Oloye titun na.

Bakanna ni nwọn yan Ọgbẹni Bayọ Tiamiyu I.ti ṣe Alakoso eto ibo yiyan awọn Oloye titun na.

Awọn ẹgbẹ ọdọ na si ṣe eto yiyan awọn Oloye titun na lọna bi owọn ṣe ngba ndibo ni ilẹ Naijiria nipa fi fun awọn ọmọ ẹgbẹ na ni iwe ti nwọn yio fi dibo.

Ki nwọn to bẹrẹ eto ibo na ni Ọgbẹni J. B Adeyemi ti o jẹ ọkan ninu ọmọ Ibilẹ Isin ni ilẹ Igbomina ṣe alaye nipa eto ti awọn ọmọ ọdọ ilẹ Igbomina ṣe silẹ lori eto idagbasoke ilẹ Igbomina eyiti o tun ṣe alaye nipa bi isowọpọ yio ṣe wa larin awọn ọmọ Ilẹ Igbomina eyiti nwọn yio fi bọ lọwọ



Ọgbẹni J K Balogun
Alaga ẹgbẹ Afẹnifẹre Igbomina

awọn amunsin ti Iṣe ẹgbẹ Olomi (NPC)

Lẹhinna ni eto ibo didi na bẹrẹ eleyi ni awọn Oloye titun ti awọn ọmọ ẹgbẹ na yan Ọgbẹni J. K. Balogun Alaga, Alabi ọba igba keji Alaga, Ọgbẹni J. A. Adebayọ ti o jẹ Alaga ẹgbẹ ọdọ Ibilẹ Isin ni awọn ẹgbẹ na yan gẹgẹbi Akọwe agba R. A: Anisẹrẹ Akapo, R. A Salami Akọwe eto Irohin, Joseph Abegunde Akọwe eto akoso ẹgbẹ, Ọgbẹni John Oyeyi ti o jẹ okan ninu Agbẹjọro pataki ni ilu Eko ni awọn ọmọ ẹgbẹ na yan gẹgẹbi Oludamọran eto Ofin, Ọgbẹni Samuel Atoyebi Akọwe eto owo, Yaya Ilesanmi Aṣiwaju ẹgbẹ ati Alfa Jimẹh Ajao lati Ilu Omupo ni awọn ẹgbẹ na si yan gẹgẹbi Imam ẹgbẹ.

Ninu ọrọ alaga titun na fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilẹ Igbomina ẹka Eko ni Ọgbẹni J K Balogun si dupẹ lọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ na pe nwọn tun yan on pada gẹgẹbi alaga ẹgbẹ na, o si tun rọ awọn ọmọ ẹgbẹ na lati mura ati pe ki nwọn si ni isowọpọ lati jẹki ilẹ Igbomina ni ilọsiwaju atipe ki nwọn le bọ lọwọ awọn ẹgbẹ Olomi (NPC) to fẹ fi ẹgbara ma ṣe Ijọba le wọn lori.

Lẹhin eyi ni Oludamọran eto ofin fun ẹgbẹ na ti o si tun jẹ ọkan ninu agbẹjọro pataki ni ilu Eko Ọgbẹni J A Oyeyi tun rọ awọn oloye titun ti nwọn ṣẹṣẹ yan na lati fi tọkantọkan ṣiṣẹ ti nwọn yan wọn si ati pe ki nwọn si ri pe nwọn nṣe ipade dede ati pe ki awọn ọmọ ẹgbẹ na ni isowọpọ larin ara wọn lati jagunmolu ki nwọn si ri mọpe nwọn ṣẹgun awọn ọta wọn ni ilẹ Igbomina eyiti iṣe ẹgbẹ Olomi.

O tun ṣe alaye pe eleyi ti jẹ ohunti o da gbogbo enia loju pe ẹgbẹ Olomi ti ku patapata bayi ati pe aye si ti ṣilẹ lati jẹki ẹgbẹ Afẹnifẹre le fi ẹsẹ mulẹ ni ilẹ Igbomina

## Lati Oju Ewe Kini

### AABO

Ninu ọrọ ọga agba awọn Ọlọpa ni ẹkun Ondo Ọgbẹni T. Ọdọfin fun Oniwe irohin wa nigbati o fi ọrọ nwa lẹnu wo lori awọn enia ti nwọn opada si ile wọn ni ẹkun Ondo bayi ni Ọgbẹni Ọdọfin si ṣe alaye pe inu on si dun lati ri pe awọn enia na ti nwọn sa kuro ni ile lati le da abo bo ara wọn si tun padabọ si ile.

Ọga awọn Ọlọpa na tun ṣe alaye fun Oniwe irohin wa pe nigbati awọn enia na pada si ile wọn pẹlu awọn Ọlọpa ti da abo bo wọn ni o ti ṣe alaye pe gbogbo awọn ẹbi, Ọrẹ, Iya baba ati ojulumo si kun fun apọ lati le ki awọn enia na ku abọ.

Ọgbẹni Ọdofin tun ṣe alaye fun Oniwe irohin wa pe awọn si ti nṣe eto lati le ri pe gbogbo awọn enia to sa kuro nilu ni lati padabọ si ilu wọn ati pe ki nwọn maṣe bẹru kankan.

Ọga agba awọn Ọlọpa fun ẹkun Ondo Ọgbẹni T. Ọdọfin tun ṣe ileri pe on pẹlu awọn ọmọ ẹhin on ti mura silẹ bayi lati ran ẹnikẹni to ba nfẹ ki a ran on lọwọ tori pe awọn enia kan yio fi iyajẹ wọn tabi pe ki nwọn si ma halẹ mọ wọn.


Printed and Published By Modupe Printin Press16, gbss Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 25 Branco Street Lagos 15 /2/66